

# Ẹ máa pìtàn

O kò nilo lati ka awọn ọrọ naa nigba gbogbo. Wíwo àti ṣíṣe àlàyé awọn ìwé aláwòrán jẹ́ ọna pataki kan lati ṣe kóríyá fún ọmọ rẹ lati maa gbádùn ìtàn. Tí ẹ bá n sọ èdè miran nílé, ẹ maa sọ ìtàn nipa awọn aworan yii ní èdè yin.

Tí ẹ bá n pín awọn ìwé kà laarin ara yin, ó maa jẹ́ fàájí fún yin papọ ni.

- Ẹ sọ nipa ohun ti n bẹ lẹ́yìn páálí ìwé naa, kí ẹ sì tọka sí àkọ́lé rẹ.
- Jẹki ọmọ rẹ mú ìwé naa lọwọ, kí ó sì máa ṣí awọn ojú-ewé rẹ.
- Gbá wọn níyànjú lati sọrọ nipa awọn aworan naa.
- Lò ohùn oriṣiriṣi fun awọn olùṣe inú awọn aworan naa. Fi ohùn dábírà fun awọn nnkan bí i omi tó fọ́n síni lára, ọkọ̀ tó n fọn fèrè tabi dídún awọn ẹranko.
- Nigba ti ìtàn naa ba tán, o lè beere lọwọ wọn pé ṣe wọn gbadun rẹ àti pé njẹ wọn ní olùṣe kan tó jẹ́ ààyò wọn.

**Njẹ o mọ̀** pé awọn ọmọdé tí àwọn òbí wọn maa n kawe sí leti nigbogbo ìgbà lákòókò tí wọn wà ní ọmọ-ọdun marun un maa n ṣe daadaa ninu ìdánwò ìṣirò ati sípẹ́lì tí wọn bá ti di ọmọ-ọdún mẹrindinlogun (16) ju awọn tí wọn kò ṣe irú iranwọ bẹẹ fun?[5]

**Njẹ́ o mọ̀** pé awọn ọmọdé maa nsaaba ní ààyò ìtàn kan tí wọn maa n fẹ́ gbọ́ laimọye ìgbà bí? Eyi maa nràn wọn lọwọ lati mọ̀ nipa ààtò ọrọ, tí wọn sì n lè so ọrọ naa mọ́ ìtàn naa – eyi tí í ṣe awọn igbesẹ àkọ́kọ́ ninu kíkàwé!

**Olobó oníràwọ̀**
Ẹ dìjọ kọ́ ihò-ẹranko (ẹ da aṣọ bò tabili), pẹlu àyè tí ẹyin mejeeji maa jọ wà. O lè kọ́ ihò-ẹranko tirẹ lati inu ìtàn naa – ó lè jẹ́ ihò iwin, ọkọ̀ rọkẹẹti, tabi ọ̀wọ́n ọmọ-ọbabinrin kan.

**Lọ́rọ̀ kúkurú**
Ba ọmọ rẹ sọrọ nipa awọn ohun tí o ṣe nigba ti ìwọ naa wà ní ọmọdé. Jẹki gbogbo ẹbí kópa – awọn òbí-àgbà pẹlu lè fẹ́ pa awọn ìtàn lati akoko tí awọn naa n dagba!